*Irohin pataki lori*

# AWON OHUN IKOLE

**O BERE ni 1956. Egbe Onisowo Portland Cement Manufacturer's Limited ran awon ojogbon isura ile wa won ile lati Ilaro de aala ile Dahomey bi yepe ti o se se simenti ba wa nibe, awon enia na si jabo fun won pe o wa nibe.**

Ninu osu Kefa 1957 awon Portland Cement Manufacturer na binnu lati ko ile ise na si Ewekoro ti o jinna ni ogoji ibuso si Eko ni ona Abeokuta. Riro igbe ibe ati kiko ile ise na fere gba won ni odun meji. Ni ojo kerindinlogbon osu keji odun 1959 nwon se akojo Egbe West African Portland Cement Company ni Naijiria. Nigbati ise na pari ni 1960 ise Simenti sise bere. Bayi ni a se ko ile ise Simenti Ewekoro ti o le ma a se ibewo re.

**APEJUWE AWON ISE NA**

Ona Eko si Abeokuta pin awon ise na si meji: Bi o ba nlo si Abeokuta ile ise na wa ni ibiti nwon gbe nwa okuta ti nwon fi nse e wa ni owo osi, wa ri awon ile ise ati awon ile egbogi nibe, ti awon moto akeru fimu-lemu lati ma a ko simenti lo fun awon onibara. Awon irin-ise nlanla ti ariwo won le di enia leti, ti o fi je ekunkaka ni wa fi ma gbo oro eniti o duro ti o. Bi o ba rin siwaju die wa ri ibiti nwon n w a okuta, wa ri ero nla ti ntule jo niwaju won ati omi ogodo ti nwon nlo fun ise simenti iru omi be e ko fi be e wulo fun enikeni. Ero iwale ati ti kiko eru wa si oke ti o ga fiofio ti nwon nko ohun elo simenti jo. Koto ti nwon ba wa nwon a si tun fi yepe di i pada.

Bi nwon ti se nse Simenti — Nwon a fi omi po iyepe po, apolu na a ma a wa yo jade nipa sise si koto, iyepe ti o ba ku nibe yio wa nibe di igba lilo o fi kan an. Awon ero ti nlo okuta-efun ati iyepe na yio ma a ta a latagba si ara won. Yiyo awon ohun elo na ni a npe ni "Slurry" okuta-efun ati iyepe yiyo d'omi, ni a ko pamo sile itoju alawo titi igba lilo.

**PIPIN KAKIRI FUN ISE IDAGBASOKE**

Ero Ase, a yo omi kuro lara re, a wa ku "ogidi." Ogidi yi ko ni gbe tan patapata ao da sinu "Noduliser" ti o ge si wewe ti a npe ni 'Nodules' nwon a si ko sinu 'Press-Heater' o di sisun ninu ebu ti a fi biriki se nwon a si ko ohun idana elepo sinu re. Iwon igbona ooru inu ebu na je 250°F. Bi o ba yoju wo inu ebu na wa ri jijona na ti o funfun, igbona-ooru mu ki elo re yipada di simenti ti o dara jade. O mu tonun mejidinlogun ni wakati kan nigbana ni o di simenti, ti nwon ba se e tan won a di sinu apo nwon a fi ami-elerin (Elephant-Mark) si i. Ni ona yi egberin-o-din adota tonun simenti ni a se lojumo ni Ewekoro ti a si fi nsowo si awon onibara.

Elephant ran Naijiria lowo fun idagbasoke. Ona kini Ile-ise Ewekoro, nse okemewa iwon tonun simenti ni odun kan (200,000 tons per year nisisiyi, ki o to to 1964 yio to iwon okemetalelogun tonun (450,000 tons) lodo-odun. Eyiti yio to fun lilo agbegbe Apapo Ijoba ati ti Ijoba Ipinle Iwo-Orun.

Eweokro ngmu simenti wa kiakia nititun ti o owo re si dinku, ni ona yi, owo ikale dinku dada, ati pe apon ise ilekiko si nle si i.

Lona keji, iranlowo nla ti Elephant nse fun esuna owo ilu nipa fifi oke marun-din-logorun ponun (£1 million) owo iraja ni ilu okere pamo ilosiwaju ati abayori ise na yio ma a gbeeru si ki owo fifi-pamo na le fi to ilopomeji si eyi. simenti rira ni ilu okere yio dinku pupo tabi ki o ma tile si mo. Owo ti nwon nfe yi yio bo si ipamo. Nwon a si ri i lo fun awon ohun elo pataki miran ti nwon ko nse ni ile yi.

Lona keta ise na da ise sile fun awon enia Egbesan onise (1,800 labourers) ni a gba larin kiko ile ise yi. Fun afikun ise, ki ise onise-ojumo nikan ni a o gba sugbon a o gba awon onise-owo ati onise ero ti a ma a ko ni ise ero. Awon onisowo ni yio si awon awa-moto si i ti yio ma a ba won ko simenti lo sodo awon onibara won ti o npo si.

—Eyi ni awon ona ti Elephant fi nran idagbasoke Naijiria lowo pelu esunna.

Lehin ise nla ati aseyori idawole yi, je itan ise ti o le gan an ati ero arojinle. Itan ile-ise Simenti Ewekoro je apere rere yi. Ile ise na tun da ise sile gan an fun awon enia, o fi kun apon ikole ilu, o si pese ohun ikole pataki simenti o mu ki inawo si ilu okere o dinku. O si je anfani pataki fun ilu Naijiria.



BI ISE SIMENTI TI SE BERE NI EWEKORO;

**R. C. IRVING & CO. LIMITED**

*Estate Agents & Valuers*

HAVE AVAILABLE

*COMMERCIAL and INDUSTRIAL*

*Sites and Buildings in Lagos Apapa and Ikeja*

RESIDENTIAL FLATS, HOUSES AND BUNGALOWS

*IN*

*IKOYI, LAGOS, APAPA & IKEJA*

**11/17 TINUBU STREET**

P. O. BOX 289

LAGOS

Telephone: 20141 20142 20143

Managing Agents for

**The Lagos Building Society Ltd.**

**The Century Mortgage Company Ltd.**

# NITORI KINI

## apo simenti yi ṣe jẹ pataki fun ilu Nigeria?

Simenti Elerin ni.

Ilu Nigeria ni a ti se, pelu ora ile yi.

Eyi ti a nse l'odun kan nisisiyi je Egberun ona igba osuwon tonnu. Sugbon o ye ki o ju ilopo meji eyi lo.

Isiro ti bere, a o si s'asele ti o ma ju Adota-le-nirinwo egberin osuwon tonnu, ni odun kan, lati le je ki gbogbo awon ara Eko ati agbegbe re pelu iwo orun le ri lo to.

Nigbati a ba bere si se pupo bayi a ni ireti pe edinwo gidi yio wa bosi sise, yio si wa je anfani dajudaju fun awon ti o nlo Simenti yi.

Nipa lilo awon ohun elo ora-ile ti Nigeria yi, ohan wipe a fi Adota-ati abo oke poun din si lilo ohun elo ora ile ti ilu ajeji lodun.

Ni odun 1964 owo ti a o fi din si ti ilu ajeji yio le ni Adojo oke poun.

Owo ti o din yi, yio ran eto idagba soke ati itesiwaju ilu lowo, yio mu aye ati le ra awon eru ati irinse ohun ti a ko iti le se ni ilu Nigeria.

Imudagba soke Simenti "Elerin" mu lilo ora ile Nigeria te siwaju.

Awon ajo West African Portland Cement Company Ltd., ti won nse Simenti "Elerin" ni igberaga pe ko si wipe awon tun ni nlati ra ohunkohun bo ti wu koje lati ilu ajeji fun sise Simenti ti Nigeria dara, dogba, bi ti gbogbo agbaiye.

**THE WEST AFRICAN PORTLAND CEMENT CO. LTD**

THE WEST AFRICAN PORTLAND CEMENT CO. LTD.

# OMO YORUBA, E RONU

Gbogbo eyin omo Odua
Edumare yio wa pelu wa
Ipinle wa yi ko ni
Di ti awon ika enia o Ase
Enyin omo Oduduwa
E teti beleje
Ki e gboro lenu mi
Nipa ti awon ika enia
Awon ti ko ro
Ti omo won lehin ola
Awon odale enia
Ti ko ro nipa
Ilosiwaju ipinle yi
Afi ki jagunlabi ma
Fe foo ninu ohun asan
Iwa won tile nrun re
Lodo gbogbo enia
Enyin omo Odua
E so fun mi
Ilu wo ni won
Ti gbe nse ijoba
Iru ti Ipinle yi
Anise ijoba a gbo koro se
Nje bi e ba mo pe
Ijoba ti o te
Awon enia ipinle yi lo-run ni
E je ki a di ibo
Ngbo o je danwo
Bi oko ba ni
Je iyan re n'isu
Se owe agba so bayi pe
Bi iwo ba se rere
Ara ki o ba ya o bi ?
Ngbo iwo odale enia
Iwa re ko lo nti o kiri
Eri okan ko je
Ki o le f'okan bale
Jagunlabi ko le to o
Lai mu soja dani
Afi bi nwon mu u lori dani
Ki jagunlabi to le je
Eri okan ko je
Ko ni ifaiya bale
Ojojumo l'Akata-nla nyo kiri
Ohun jagunlabi se
Ko fi lokan bale
O ti so ara re di
Ohun nwon ngba kiri
Lori papa l'abule wa
Eyin enia mi
Ore won na yio re ja
Fun apere
Ni aipe yi ni
Alakoso ijoba ibile
Fi agbara tu ijoba
Ibile medogbon ka
Lai ko ka
Esun kan si won lese
A ki binu ori
Ki a fifila de idodo

## LATI OWO – ADABA

Mo fe fi asiri oro kan
Setigbo t'omode t'agba
Ohun ti ijoba Olomi
Ati ijoba Aladie
Nko bo wa ba yin
Ti e ko tete
Kiyesi ara
Se rikisi lo pa nwon po
Ti nwon fi di ore
Laipe laiko si jinna
Nitoripe egbe Afenifere
Lo nse akoso won
Ni o mu ki o
Lo agbara re ni ilokulo
Iwon ni nkan mo
Gbogbo iwa eda l'aiye
Ni yio j'ere re
Ore jowo ranti pe
Nebukadinesari ti se oba Babeli
Lo agbara nilo kulo bayi

Kini o sele si ?
O di eranko
O si je eweko igbe
Fun odun meje gbako
Eleyi to eko
Fun t'emi t'ire
Nje nitorina
Enyin omo Yoruba
Akoko to fun nyin
Lati mo pe
Nwon ko fe ire
Fun nyin ati omo nyin
E jeki a jo fi
Oju inu wo ijoba
Egbe Afenifere
Ni Ipinle yi
Ani ki o to di
Ti awon ika enia
Gbogbo wa ni a mo daju

Pe Oloye Awolowo
Lo se eto eko ofe yi
Lai ko fi kun
Owo ori mo ti
Ohun gbogbo nlo leto leto

Ara de gbogbo enia
O se eto
O tun fi owo kun
Owo osu awon oluko
Fun ekun rere idera
Sugbon nigbati o di
Ti awon alagbara nko
Ani se asiwaju
Egbe olomo-kuya
Fi kun owo ori
Lai ko ba nyin ro
Ibi ti e ti ma san
Ise ko si
Oja ko si ta
Ijoba jagunlabi
Ni enia lara koko
Bi oju eja
Ogede nbaje
E lo npon
E ko mo daju pe
Oju ti yio bani kale
Ki iti aro se ipin
Nje enyin enia ipinle yi
Bi e ba nfe
Ekunrere idera
E jina si awon
Alagbara ma m'ero
E jina si egbe olomo-langidi
Bi ale yio ti ri
Aro ni ati mo o
Ibere won ko dara
Opin won ki yio suwon
A ti gbe ijoba koro yi
Si ori iwon
Beni ko si to iwon
Opin won de tan
Oro Olorun so bayi pe
Emi nbo kankan
Ti emi t'ere mi lowo mi
Lati san fun olukuluku
Gege bi ise re
Iba se rere
Tabi buburu
Nje mo wa bere ?
Iwo alagbara esin me-dogbon
Kini ipin tire o ?
Nje ki nto gbe ti odale ti
E jowo e ba mi gbe'rin
ORIN :-
Ko wabi gba o
Ko wabi gba
Akata-nla gberu re
Ko wa bi gba o.
Ipade di ose t'ombo o.
O di gba.

## AWỌN OGBOLOGBO IRORA ORIKE-ARA TI LỌ!



KRUSCHEN SALTS NLE AWỌN IRORA ORIKE-ARA ATI LAKU-REGBE LỌ O NFỌ EJẸ MỌ. A SI MU OKUN TITUN WA SI ARA RẸ !

Elere alogida kan ti o yara kankan, ti o si ti wa ninu egbe awon elere gbogbo agbaiye !!! Şugbọn ti akoko kan ko ni agbara to lati bori idije. Nigbana ni o wa KRUSCHEN SALTS kan. "Eyi ti jeki gbogbo nkan yipada," o ni. "Ọna titun lati ti bori idije nkan ko ni mo ri, mo tun pa oro awon esunra orike-ara pelu lẹhin ti mo ba kọ ere igi-fifo kikan-kikan tan."

O le ma je alagbara-elere-ije, sugbon iwo na le ri anfani nipa mimu ẹkun sibi Kruschen Salt kekere kan lojojumọ.

Nipa fifo ẹjẹ mọ, Kruschen Salt yio jeki o ni ilera ki o si lagbara !!! Yio si fun ọ ni agbara titun fun igbesi-aiye rẹ.

Fi ẹkun-ṣibi alafia kan sọ ẹmi rẹ lojọ.
MU




# KRUSCHEN SALTS

# AKINTOLA

(Lati oju ewe kini) se lori oro gbese ti Oloye Akintola ati Oloye Awolowo je na lo bayi : £40,000, £150,000 £250, yi ni ojo keta osu kerin odun 1961 ati ni ojo ketala osu kefa odun 1961.

Ejo ti Egbe Onisowo NIPC pe si ile ejo giga l'Eko ni owo ti awon mejeji ya ni ojo kejile-logun osu keta odun 1961 si ojo kerindinlo-000, £250,000, £100 000 ati £200,000 apapo owo na si je £1,370,000, iye ti won san ninu re ni £331,801: 17: 2d. Egbe Onisowo NIPC ya awon mejeji na ni owo gun osu keta odun 1962 je asanku £161,210.

Alaye gbese ti egbe Onisowo NIPC se lori oro ejo ti nwon pe Oloye Akintola ati Oloye Awolowo l'ejo si Kotu Giga Ikeja lo bayi :- £200,000, £600,000 £180, 000 £100,000, £40,000 £35,000, £50,000 £50,000 ati £100,000.

Ohun ti o ki Egbe Onisowo NIPC laiya lati fi pe awon mejeji na l'ejo ni imoran ti o ti odo awon amofin ti nwon gba ni ilu oyinbo wa lati tu abayorisi Igbimo Iwadi Coker wo nipa iwadi ti nwon se lori oro awon Igbimo Ajo Ise Ijoba Ipinle Iwo Orun mefefa ninu odun ti o koja.

Egbe Onisowo NIPC si kowe si Alhaji Shehu Sagari Minista Alakoso eto ise arin ilu pe ki o gba awon laaye lati mu amofin ile geesi kan wa si Naijiria ti yio se asiwaju awon amofin Naijiria ti nwon ngbe-nuso fun awon ninu ejo na.

Oruko awon amofin mejeji na si ni ojogbon Magerry ati Ogbeni A. R. Rink.

Ohun ti nwon fe faye ninu ejo ti nwon pe na ni pe, "Boya ofin mu enikeni ti o ba fowo soiya ya owo loruko egbe gegebi onigbese, ti ko ba si ninu ofin egbe won pe nwon le ya owo."

Gbigbo ejo ti Eko si di ibere osu kerin odun yi.

# ALA ATI ITUMO

## Lati owo — Joseph Alala

EMMANUEL T. OYẸDELE, ABEOKUTA—Ti o ko ba ṣora gidigidi laseko yi aisan ojiji yio kọlu ọ. Ko si tun ṣora lọdọ ki oran ọlọran ma ba a di tirẹ.

JOSEPH OWE, LAGOS—Akopọ ala ti o la ko dara rara, ṣora gidigidi laseko yi ki aisan ojiji ma ba kọlu ọ. Ki o si tun ṣora lọdọ awọn ọrẹ nipa fifi inu rẹ han wọn nitori ijamba.

BABALỌLA FAPOHUNDA, IBADAN—Ala iṣegun ni eyi, ohunkohun ti o ba si dawọle laseko yi rere ni yio jasi.

ABRAHAM ỌLAJIDE, ONDO—Iwọ yio padanu ohun ini rẹ laipẹ yi ti o ko ba ṣora gidigidi, si kun fun adura laseko yi ki awọn ẹni ibi aiye ma ba a lagbara lori rẹ nitoripe nwọn ndọdẹ rẹ lati ṣe ọ ni jamba.

TINUKẸ ỌMỌLARA ẸKUNDAYO, ỌTTA—Igbẹkẹle rẹ ko ni jasi asan lasekọ yi, ṣugbọn ṣora gidigidi lọdọ awọn ẹbi rẹ.

JOSEPH ADEYẸMỌ, IBADAN—Maṣe bẹru rara, itumọ ala rẹ ni ẹmi gigun ati alafia ara, ṣugbọn ṣora lọdọ awọn ọrẹ rẹ ki nwọn ma ba fi ọbẹ ẹhin jẹ ọ ni iṣu.

YẸKINI ADEJỌBI, IWO—Ibanujẹ rẹ yio di ayọ laipẹ ojọ.

FATUROTI ADẸYẸMI, BENIN—O nilati ṣora gidigidi laseko yi, ki owo awọn eni ibi ma ba a to ọ lati ṣe ọ ni ibi.

BAMGBELU ADEDỌTUN AKWATIA, GHANA—Gbogbo oke iṣoro rẹ ni yio di pẹtẹlẹ fun ọ ti o ba ni suru.

AKANBI EGUNJỌBI, KADUNA SOUTH—Aisan ojiji yio kọlu ọ, sugbon ti o ba kun fun adura, aisan na yio rekọja.

AKIYESI: Iwo paapa le fi ala ti ọ ba la ransẹ si:—
JOSẸFU ALALA, Irohin Yoruba, 214 Broad Street, Lagos.

# OYE A M'ORI O




*IROHIN koto ajojuba ni wiwe lawani oye Baalẹ ilu Tomu ati agbegbe rẹ ti Ọmọ-Ọba Eko, Oloye Aminu Kosọkọ, Asajọn Olọja Ereko we fun Oloye Mọmọdu Tiamiyu ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu kini ọdun yi, ni Aafin Kosoko.*

*Bi Ọmọ-Ọba Eko, Oloye Aminu Kosọkọ ti gunnu rẹpẹtẹ si Aafin rẹ ti o si fẹ lati ṣe eto fifi Oloye Mọmọdu jẹ oye Balẹ nṣe ni awọn ara Tomu ati Ẹbi Oloye Kosọkọ bẹrẹsi gombo Oloye Kosọkọ, alẹwọ si gbotikan nibẹ. Lẹhinti nwọn ti fi jẹ oye Baalẹ tan, ni o si sọrọ pe, lati igba iwaṣẹ ni ilu Tomu ati agbegbe rẹ ti wa labẹ Ọba Kosọkọ. Awọn ara Tomu ko si gbọdọ da ukankan ṣe lai gba aṣẹ lọwọ olori ẹbi Kosọkọ.*

*O si dupẹ pupọ lọwọ Oloye Kosọkọ fun ọla ti o fi da a, o si ṣe ileri pe, pẹlu ogo Ọlọrun on ko ni yi aṣẹ rẹ lori Tomu pada. Oloye Kosọkọ si pa a laṣẹ pe ki ọkan ninu awọn ẹbi on we Mọmọdu ni Lawani oye. Lẹhinna ni o si fi ọpa oye ti o dara pupọ fun fun, o si fun un ni fila onidẹ gidi. O si se ase rẹpẹtẹ fun Baale na ati awọn alabaṣeṣe ọjọ na, ajẹli ati amuti ni nwọn fi onjẹ adidun ati orisirisi oti ọjọ na ṣe.*

# ALAPARA IBADAN

**(Lati oju ewe keji)**

fowo s'oiya pe awon ni igbekele ninu egbe Olope ati Oloye Obafemi Awolowo babasale egbe na

Olotu: Mo fe ki o mo daju pe, omo Yoruba gidi ti o ba ni on kasa s'egbe UPP ati NCNC ki i se Omo Odudua Bi gbogbo ilu tile ngbojege fun awon egbe ipinle mejeji na, omo ori igba ni nwon je ni Ile Ife, nwon ko si le ri idi joko nibe lailai

Alapara: Laipe yi ni awon kan tun mu irohin ..o si ile ero asoromagbesi pe, on ti Oloye Oye tun jadi iro l'egbe Olope sile w'egbe Oniyoro O ni iro patapata ni irohin na, atipe lojokojo t'egbe Olope ni on nse

Olotu: Ajegbodo w'eni kunra" ni oro ti NCNC ati UPP, dabi moti da si ni won, eniti yio da idaku..a bi tiwon ni nwon nwa

EWURE BI IBEJI TI O LEPO

Alapara: Nje o gbo nipa ewure ti o bi t'ako t'abo omo, ti awon mejeji si lepo ?

Olotu: Bee ni tire ri Alapara, iwo nihin, iwo lohun, iwo kanna nibi gbogbo, nibo ni ewure titun bi omo ti o lepo o ? Ti omo enia meji ti o lepo ni Kano ni mo ti gbo ri nko ti gbo ti omo eranko a fi eyiti o so yi

Alapara: Puro ki ngi-niyi ete ni i ..nu wa, ni ilu Algeria ni

Olotu: Ise Olorun awamaridi ni, bi o si ti wu u ni O nsise re

AWO YIO LEKE LAGBARA OLUWA.

Alapara: Nwon iba gun Awo l'odo, ki nwon lo l'olo, lagbara Oluwa lagbara Odua ati otito inu, baba Layinka yio bori awon ota re.

Olotu: Gbo orin kan ti awon Sanmori Eko ko laipe yi pe
Ibiti nwon ni ki
Gbegbe ma gbe
Ni i igbe titi
Ibiti nwon ni ki
Tete ma te
Ni i te pe
Awolowo baba 'Yinka
Lo ni West
Ope lo ni West
Lojokojo Awo
Lo ni West
Laiseaniani alajobi yio gbe Awo l'eke isoro re laipe ojo Alapara, O digbakanna o, ka fi're pade lose to mbo o, lagbara Oluwa


# £2,500

*to be paid out in prizes in the*

**FIRST NATIONAL**

**PREMIUM BOND DRAW**

*Monday, April 1st, 1963*

You must get your Bonds before the end of March to qualify for a chance in the NEXT £2,500 draw to be held in July.

Bonds may be bought for £1 or £10 at any Departmental Post Office or Commercial Bank. Three months after the date of purchase your Bond becomes eligible for EVERY subsequent quarterly Prize Draw and at the end of the Premium Bond Scheme the owner of every Bond gets back the whole sum of money originally invested.

**BUY IN MARCH**

**FOR THE**

**£2,500 JULY PRIZE DRAW**

# OLASOPE ATI SEGUN SMITH NI ILU OYINBO



Ile ise Telifisan kan ni Londonu mu awon akowe irohin ni redio Naijira yi ile ise won ka.

Ogbeni Emmanuel Abiola Olasope Olotu Irohin Nigerian Broadcasting Corporation Lagos ni o wa ni apa osi ninu aworan yi.

Eniti o wa ni aarin ni Ogbeni Olusegun Oladeinde Smith. Olotu Irohin Ile Ise "Nigeria Broadcasting Corporation" ti Ipinle Iwo Orun Naijira.

Ogbeni Rowan Ayero Igbakeji olori ile ise aworan asoromagbesi ni o nfi okan ninu awon Kamera na han won ninu aworan yi.


## DA IKO OTUTU DURO

Ti o ba nwukọ tabi o ngmi tipatipa ti o kọ si le mi dele tabi sun dada nitori iko-ife tabi amodi imu tabi iko-otutu ti o mba e ja. Lo ra MENDACO loni ni ile itaja-egbogi MANDACO ma a susẹ ninu eje ati iho ọna ofun lati fọ gbogbo kelebẹ ti o ba di sibe. Nigbana ikọ rẹ a fuye, wa a si le mi dada wa a si ma a sun bi ọmọ-ọwọ wa gba agbara rẹ gan an pada. Bi ko ba jẹ bẹ ẹ, a se ileri lati da owo rẹ pada. Lọ ra MENDACO loni lọdọ onibara rẹ ti o nta oogun.


OLOYE FADAHUNSI WIPE:

# Awon Aditi ati Odi nfe iranlowo

**OLOYE J. O. FADAHUNSI, Gomina Ipinle Iwo Orun Naijiria kan saara si Ibadan Mission School fun awon aditi nipa eto itore anu ti nwon se ni gbongan Obisesan ni ojo kejidilogun osu keta odun 1963.**

Gomina na tun yin awọn oludasilẹ ile iwe na fun eko ti nwọn nko awọn odi ati aditi na ki nwon ba je di enia nla lehin ola gegebi awon elegbe won miran

Siwaju Gomina na ro awọn enia alarojinlẹ ilu Naijiria pe ki nwon fi tokan-tokan ati tife-tife ta Ibadan Mission School fun awon Aditi lore nipa fifi owo ranṣẹ si.

Ibadan Mission School for Deaf, P. O. Box 808 Ijebu Bye-Pass, Oke Ado, Ibadan Nigeria. 'Ibadan Mission School' fun aditi ni o je ibugbe ati ile eko fun awon aditi ni Ipinle Iwo Orun Naijiria.

# OYE KO FI EGBE OLOPE SILE

**OLOYE J. O. OYE, Minista alakoso eto Eko atijo ti ise asoju Akoko-Oke ninu Ile Igbima Asofin Ipinle Iwo-Orun jadi iro ti enikan lo pa ninu ero asoromagbesi pe, on ti kuro ninu Egbe Olope bo sinu Egbe Alakuko.**

Nwọn ka irohin irọ na lori redio ni agogo meji abọ osan ọjọ Iṣẹgun ti iṣẹ ọjọ kejila osu kẹta odun yi. Lẹsẹkẹsẹ ti Oloye Oye gbọ irohin na ni o ti so pe ko si ododo kan ninu ọrọ na ati pe lojọkojọ ẹgbẹ olopẹ ni on nṣe, on ko fi igbakan kuro ninu ẹgbẹ na bọsi ẹgbẹ Alakuko.

Oro ti Oloye Oye sọ nigbati o wọ ile iṣẹ Iwe Irohin wa ni pe, "Nko ni ero lati fi Ẹgbẹ Ọlọpẹ silẹ rara, o le jẹ pe awon okumarata ọmọ ẹgbẹ Alakuko kan ni o fi bojuboju mu irohin irọ na lọ si ile iṣẹ redio." Oloye Oye si kilọ fun iru awọn enia ibi bẹ ẹ pe ki nwọn dekun lati ma a ba on ni orukọ jẹ.




Iwọ ha lè gbe iyawo bi? Iwọ le ṣe bẹ laipẹ lọ titi bi o ba bẹrẹ lati ma f'owo pamọ ni ọdọ Barclays nisiyi!

"IGBEYAWO NA"

Barclays Bank ti ṣẹ awọn aworan sinima eyiti idanilaraya to si wunni lati ma wò, boya iwọ papa ti ri tẹlẹ. Aworan ti anpe ni "IGBEYAWONA" jámọ itan ọdọmọkunrin kan to fẹ gbé arẹwa omidan ti anpe ni Alakẹ n'iyawo. Sugbọn baba Alakẹ kò gba!



Ọdọmọkunrin na ti orukọ rẹ njẹ Kwesi lọsi ilẹ okère lati kọ iwe ati lati ma f'owo pamọ bi agbara rẹ ti mọ. Nigbati o si pada, ohun to kọkọ ṣe nipe, o bẹrẹ if'owo pamọ sinu banki ti Barclays. Larin akoko yi, siun lo kù ki okunrin buburu kan ji olufẹ rẹ gbe lọ.



Latigba dogba ro ki o ma f'owo pamo, ki o si toju rẹ s'ile ipamọ owo. Fi ọkàn tán Barclays nipa itoju owo re, eyiti iwo yio si gbà pada yio si ju iye ti o fisibẹ lọ! *Lo bère* ni banki ti Barclays tombe nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo re pamo. Awọn ni yio fun ọ ni imọràn ati iranlọwọ to darajulọ.

Sugbọn gbogbo rẹ yọri si ayọ nikẹhin nigbati Kwesi mu gbogbo ẹbi na-pẹlu ọkunrin buburu yen-lọ wo iye owo rẹ tombe ni Barclays Bank.

Iwọ na gbọdọ bẹrẹ lati ma f'owo pamọ, nnoripe igbeiyawo ama ná enia f'owo lọpọlọpọ!

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile ise won mbe kakiri nile yi*

# EKO OFE NPARE LO?

## 'GBENRO F'EJO SUN AWON ADIBO

**LENULOLOYI ni asiri Ijoba Egbe UPP ati NCNC tu lori oro dida egbaata olukoni duro, ki nwon si pa eto iwe eko ofe ti o ti wa ni odun kejo sehin re.**

Ninu oro ti o so pelu ipade awon oniwe Irohin ni ojo kokanla osu keta odun yi, Oloye D. S. Adegbenro ni Ijoba NCNC ati UPP ti pinnu lati pa eto eko ofe re ni Ipinle Iwo Orun.

Ijoba Oloye Awolowo babaale Egbe Afenifere ni o da eto eko na sile ninu odun 1955.

Siwaju si i, Alhaji Adegbenro so pe ti o ba seese fun won lati dabaru eto eko ofe ni Ipinle Iwo Orun, a je wipe awon obi yio beresi ma a sanwo ile iwe omo won ni opin odun 1963 si 1964. O si gba awon enia Ipinle Iwo Orun ni imoran lati doju ija ko ohunkohun ti o ba le mu idina ba eko ofe awon omo won ni nitori ki igbesi aiye won ba le dara lehin ola.

Siwaju si i, Alhaji Adegbenro ni ipinnu awon apapo egbe mejeji na ni lati ri pe egbaata oluko di alainise.

### IBO TITUN

Alhaji Adegbenro si fowo s'olya fun awon enia Ipinle na pe iru ibaje yowu ki nwon le se pelu eko ofe laseko Ijoba tiwon, "mo fe ki e mo daju pe nigbati Ijoba Ipinle Iwo Orun ba tun pada si owo Egbe Afenifere, gbogbo nkan ni yio pada si aye won bi ti atijo." Opolopo nkan miran ni o si tun menuba ninu ipade re na pelu awon oniwe Irohin. Ogbeni J. A. Odebiyi pelu awon asoju ninu Ile Igbimo Asofin Ipinle Iwo Orun meta nlo wa si ibi ipade na.

Alhaji Adegbenro ni eto ni lati tu Ile Igbimo Asofin Ipinle Iwo Orun ka, ki nwon si di ibo titun ni Ipinle na ki awon enia le ni anfani lati yan Ijoba ti nwon nfe. O so idi meta ti NCNC ati UPP fi mberu lati pe ipade Ile Igbimo Asofin Ipinle Iwo Orun tabi lati dibo titun.

Ekini, o ni, Ijoba ajumosepo na mo dajudaju pe awon alatilehin omo Egbe Afenifere ti o mbe ni Ile Igbimo Asofin yio bori won.

Ekeji, o ni, eru mba Ijoba ajumosepo na lati gbekele awon omo Egbe Olope ti nwon ti fi etan famora pe lojokojo ni ni nwon le ja won tile.

Eketa, Alhaji Adegbenro ni, edeaiyede wa larin awon Ijoba ajumosepo mejeji na nitoripe Oloye Akintola fe le ife ara re lorun nipa ibo didi ni Ipinle Iwo Orun, sugbon Ogbeni Fani Kayode "ti o ngun Akintola l'esin kakiri Ipinle na pelu 'igbadun ni, oro ibo didi koi ti w'aiye ni Ipinle Iwo Orun na."

O si tun fi nye awon enia Ipinle na pe, lojokojo ati ni igbakugba ni oro ibo didi le b'ehin yo nitorina ki gbogbo won wa ni imuradie.

Nipa oro ti enia kika ti nwon se ninu odun 1962, Alhaji Adegbenro ni, eyi fi han gbogbo agbaiye pe, bi Naijiria ti tobi to, ti o si lokiki to, sibesibe nwon kuna lati ka awon enia won pe yekeyeke. O ni eto ni lati le jeki abayorisi enia kika na di mimo fun gbogbogboo ninu Iwe Irohin, yala Egbe NPC ni o gbe fun ni tabi ko gbe fun won.

Alhaji Adegbenro ni nipati oro Ipinle Agbedemeji Iwo Orun, "Egbe mi ti mura tan lati run sparun ese si pe seese.

Ni ipari oro re, Oloye Adegbenro se ileri marun ti Egbe Olope gbodo mu se ti Ijoba Ipinle Iwo Orun ba pada si owo won.

(a) Ile Iwe eko ofe ti awon obi ko fi ni maa san owi ile-iwe.

(b) Fifun Ijoba Ibile ni agbara ati maa se ilu funrara won bi o tile je pe egbe iselu olukuluku yato.

(d) Ibowo fun awon oba ati awon ijoye Ipinle Iwo Orun Naijiria.

(e) Awon oba ni yio ni ase lati maa tokasi aaise oba tabi ijoye ijoye elegbe won.

(ẹ) Fifi kun owo koko bi ti atehinwa ki Oloye Akintola to tewo gba Ijoba Ipinle Iwo Orun.

★ **Ikede Ijoba Iwo Orun Naijiria ti se esun ti Alhaji Adegbenro fi kan won n'pa pipa eto eko ofe re.**

**—OLOTU**

**Late Classified**

**Trade Notice**

PRINT your Yoruba Literatures with correct Accent Type, at REMILEKUN PRESS. Box 69 Mushin, Lagos.

## EGBE ONISOWO '7 UP' DABIRA

**BOYA o ko mo pe awon nkan iyanu ko ie tan? The Seven-Up Bottling Company, Apapa se ere-ariya miran ninu ogba won ti o fania mora ni ehinkule ile ise oti won l'Apapa ni ojo Kejo osu Keta odun yi (March 8, 1963).**

Awon onijo iyanu ni o yika agbo-ere na Egbe onilu ibe ni Bobby Benson olokiki osere Naijiria ti gbogbo aiye ti mo. Ogbeni Bobby Benson paapa ti o je asiwaju awon elere Naijiria ni o nto awon enia re sona. Iran wiwo iyanu ni, o si ju egbe-edogbon (over 5,000) awon enia ti o wa sibe lo. Awon ti o je ebun idije nibe ni awon ti o ni ideri-igo Seven-Up ti o poju. Ere-ariya ti a nse lose meta-meta na ti di ohun ti gbogbo enia ngbadun ju ati gbogbo enia ti ko le wole nitoriti nwon ko mu ideri-igo tiwon lowo tete sare pada lo sile, nwon si tete pada pelu awon ideri-igo won eyiti o je pe mefa pere ni nwon ni lati fi wole.

Okan ninu awon osise Seven-Up Bottling Company si se alaye idi ti nwon fi nse ere-ariya yi fun gbogbo awon ti o wa sibe ati awon onibara won kakiri ilu pe nwon mo iyi ise ti awon enia Seven-Up ti se lati mu oti idera yi olomi didun wa si Naijiria nipa fifi ebun ti o joju fun awon enia ti o ni ideri-igo Seven-Up ti o poju.

Awon ebun bi Sport Raleigh Bicycles, Phillip Radios, Wall clocks, fanciful stretching Combs, Sport Tennis Shoes ati beebeelo wa ninu awon ebun ti awon ti o wa na gba.




Published by the Eastern Post Limited Elephant House 214 Broad Street, Lagos and printed for them by the Amalgamated Press Ltd 5/11 Apongbon Street Lagos. Acting Editor (Adele Olotu) E. O. OLOFIN N2/439 Shitta Street, Ibadan.